# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. NO. 26. SATURDAY, JANUARY 6, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### ABOGUN-LOKO, EJIGAN-MOGUN!

A ṣopẹ lọwọ Ọgbẹni wa, Dada Adeṣigbin Ajanaku-bi 'ru-ba-mba, fun Iwe-ika-ọjọ oṣu ti ọdunni, to fi ta wa lọrẹ ọdun. Aworan Ọgbẹni Ọlọla wa, Ologbe, "Kirisi" C.M.G. ẹni-nla ti awọn enia nki ni "Abogun-loko" ati itan ṣoki nipa igbesi aiye rẹ lo mbẹ ninu Iwe na. Ile ti ko ba ti ni Iwe-ika-ọjọ-oṣu yi ṣi wa ni ipo ile "pa-la-nta."

### A LE FI ỌDUN MẸWA PILẸ IWERE.?

O nlọ si ọdun meji nisisiyi ti Ijọba wa nibi ti ka gbogbo awọn enia to wa ni Nigeria: titi di oni a ko ti ri Irohin iṣẹ na ka, a ka lọ si ile Babalawo bi?

### DOHERTY, ẸNI A FẸ LA MỌ, A KO MỌ ẸNITI O FẸ NI!!!

A ba ọrẹ wa KOLAJO DOHERTY, *Lawyer*, yọ fun biberẹ iṣẹ rẹ pada ni ọjọ kẹjọ oṣu ti o kọja, lẹhin igbati awọn Ogunna-gbo-ngbo ninu Ofin ti da duro fun oṣu mẹfa, nitori ẹṣẹ ti a gbọ pe o ṣẹ Ofin. A damọran fun ọrẹ wa yi ko ma dẹkun ati ma "difa" yi lararọ, "Ma fi ti rẹ kọ mi lọrun, lo da f'ekan on owu'.

## AROWO-ṢEFUJA, ỌMỌ ỌLA GORI-ỌLA.

A dupẹ lọwọ ọrẹ wa "Arowo-ṣefuja" fun ṣile mẹwa to fi sọdun fun wa ni lọlọyi: Ibukun Oluwa.!

## O ṢEUN, A-TO-TILE-TỌ.

Ọpẹ lo yẹ ọrẹ wa Ọgbẹni Akin Adeṣigbin fun Iwe-ika-ọjọ-oṣu ti ọdunni to fi ta wa lọrẹ laipẹ yi, Ọwọ a r'oke o!

## ẸNYIN BỌKINI TO NGBA "EKO-AKETE" Ẹ PE WA L'ENIA.

A kesi awọn Gbajumọ wa ti owo wọn fun gbigba "Eko-Akete" ti tan ki nwọn maṣe jafara lati fi owo miran ṣọwọ fun ti ọdun titun yi. A o dupẹ ti awọn ara wa yi ba le tete da wa lohun: a si nfẹ ọgọrọ enia ti nwọn ko ti fi owo ṣọwọ lati ma gba Iwe-irohin "Ilufẹmi" yi ki nwọn ma fi eni-d'eni ki a to gburo wọn. A dupẹ pe okiki ti Iwe-Irohin yi ni tubọ npele si kakiri ibi gbogbo. "Gele ko dun bi ka mọ ọ we." O di ọwọ nyi o amu-lele. Ẹ gbọ bi awọn ara wa loke ti ma nlu Dundun "Bo ba bajẹ, iwọ,! Bo ba bajẹ, iwọ!!" Ọlọrun ma jẹ ko baje.

## ATABA-TIBI.

A sọpẹ lọwọ Ọgbẹni ọrẹ wa kan ti a npe ni Munro Work ti America fun Ijimi Iwe kan *Negro Year Book for 1922-1923* ti o fi ranṣẹ si wa ni ọsẹ diẹ to kọja, Iwe yi sọ "boto" nkan ti awọn ọmọ-iya wa ni ilu okere yi ti ṣe, o si dabi eyiti awa papa nṣe fi a npe ni *Nigerian Who's Who* to nsọ iṣesi awọn pataki ninu awọn ẹni ti wa na nibi.

## Ẹ KU EWU ỌDUN TITUN.

A ki gbogbo awọn ara wa kakiri ibikibi, Ẹ ku ewu ọdun titun yi. O dabi ẹnipe a ri aperẹ bi ọdun na yio ti ri, nitori ni arọ ọjọ *Monday* ọṣẹ yi to nṣe ọjọ kini, oṣu kini ọdun titun na niwọn agogo mẹjọ, ojo kan rọ gẹgẹbi "Ojo Ibukun" o rin ilẹ fun iṣẹju di ko to da: ki eyi ma ṣai ri bẹ fun t'ọkunrin t'obinrin wa, Aṣẹ.

## ỌLA-NREWAJU.

A ba Ọgbẹni Ọlọla D. C. Cameron Sẹkitẹri Pataki ti Ijọba Nigeria yọ fun ọla ti Ọba King tun da ni lọlọyi, gẹgbi a ti ka ni "Waya" (*Reuter's Telegrams*) ti ọjọ keji oṣu yi. Ọla ti a da a ni fifun ni oye K.B.E. eyini ni Ọga-oye ti Ijọba Ge... ni gbogbo agbaiye.

## ẸTA-OKO.

Mrs. Bernice Morgan ọmọ Ọgbẹni William A. Thompson, gbẹna-gbẹna ati atun Organ ṣe, ologbe, ati alarede rẹ, li Ibẹta-ọkunrin kan ati obinrin meji—ni ọjọ *Wednesday* ọsẹ yi ni ita Ẹlẹiyẹ (*Massey Street.*)

A gbọ pe alafia ni awọn "alejo" na wa pẹlu iya wọn.

Lati ọwọ Akirimanu.

## ẸNIKẸNI TI O BA FORI TI IPỌNJU YIO DE ADE OGO.

Ni akoko kan ọkunrin kan wa ti o nṣe akuṣẹ ti o ni aguntan kan ti on ma nfi sọrọ; nipa bẹ o dide nijọkan o tọ Ọba ilu lọ o si sọ fun pe on ni agutan kan ti on ma nba sọrọ bi enia. Nigbati Ọba gbọ eyi o ya a lẹnu pupọ tobẹ ti o fi ṣe ileri pe bi ọrọ na ba ri bẹ on yio jin pẹlu ọrọ pupọ ati pe on yio de ade funi bi igbakeji on. Ọkunrin akuṣẹ yi ṣe ileri pe o da on loju ati pe ki Ọba ki o pe gbogbo ilu rẹ jọ ni ijọ meje on yio si mu agutan on jade wa sọrọ ni gbangba loju gbogbo enia. Lai fagun ọjọ na pe ọkunrin yi si mu agutan rẹ wa si gbangba niwaju Ọba ati awọn ara ilu lati mu ileri rẹ ṣẹ, nigbati ọkunrin yi si bẹrẹ si ba agutan rẹ sọrọ agutan na ko da lohun gẹgẹ bi on ti ma nṣe ninu ile, ọkunrin yi si tun ba sọrọ ni ẹkeji ṣugbọn agutan na ko da lohun. Nipa bayi Ọba binu pupọ o ti

paşẹ pe ki awọn ọmọ-ogun lọ da ina ki wọn si fi ọkunrin yi ra ina na ni ẹmẹta ki wọn si ju si fun eke ti o ti wa şe niwaju on pẹlu ara ilu. Bayi ni awọn ọmọ-ogun wọnyi lọ wọn si da ina na wọn si mu ọkunrin y i wọn si fi ra ina ni ẹkini, ọkunrin yi si tun pe agutan rẹ o si wi fun pe "agutan o ma ndi oju iku nlọ o," şugbọn agutan ko da lohun bẹni ni ẹkeji ọkunrin yi si tun wi fun agutan rẹ gẹgẹ bi ti işaju, nigbati o di ẹkẹta ti awọn ọmọ-ogun gbe ti nwọn si fi ra ina ti o si ku ki wọn ju si ina, agutan yi wa dahun lojiji o si sọ fun Ọba pe ki awọn ọmọ-ogun dawọ duro nipa iba ọrọ diẹ inu Ọba dun pupọ o si mu ileri rẹ şẹ o sin jin ọkunrin yi lọpọlọpọ ọ si de ni ade. Lẹhinna nigbati ọkunrin yi de ile pẹlu agutan rẹ o si bere lọwọ agutan na pe eşe ti o fi fẹ pa on şugbọn agutan na wi fun pe on ko fẹ pa ọ o si wffun pe "Ẹnikẹni ti o ba le fi ori ti ipọnju, yio de ade ogo."

Eyi fi han wa pe ẹnikẹni ti o ba jiya lori otọ yio jẹ ọrọ nigbẹhin.

Ọrọ mi re o ẹnyin ara ilu ẹ ku ọdun ẹ ku iyedun o.

— —

Ọfa Station,
21st December, 1922.

Alagba,

Ninu Iwe Irohin ọsọsẹ (Eko Akete Vol: 1. No. 21 Dec. 2, 1922) ewe to bẹrẹ "Gbohun-gbohun" inu mi dun pupọ nigbati mo ka iwe yi, mo dupẹ lọwọ *Police Magistrate* ati awọn ọmọ işẹ rẹ ati lọwọ oniwe yi.

Bi o ba wu Ọlọrun, ngo fi owo iwe yi ranşẹ ti yio bẹrẹ ọdun tuntun 1923.

Nipa ofin yi, nitori t'ara mi, ati awọn elomiran inu mi yio dun pupọ pe ki ofin yi ko de apa ọna oke, nu lu bi Ọfa tabi titi lọ. Nipa şişe bayi, alafia yio de si ilu wa. Ni ilu yi ọpọlọpọ obinrin lo wa ti ko ni ọkọ ti yio tọrọ ile funra rẹ ẹnikẹni to ba fẹ yio ma tọ ọ lọ ninu ile to tọrọ na. Ọpọlọpọ ninu awọn ara wa to fi ile ati ọna wọn silẹ ni ọdun jọjọ ni iru awon obinrin wọnyi ko jẹ ki o ranti ile mọ. "Owo ko si ajo buşe" nigbati ko ba si owo lọwọ, gbogbo ero rere a pin mọ oluwa rẹ ninu.

Yio si dara pupọ fun ire ilẹ wa pe ki *Police Magistrate* ati awọn ti o tọ, şe ni ofin pe ki awọn Ọba ilẹ enia dudu sofin fun Bale-bale ti ilu wọn pe ki nwọn ma ma gba obinrin abilekọ sile lairi ọkọ rẹ tabi ki nwon mọ bi obinrin na ti rin ko to de ilu na. Iwe ti mo tọka si loke sọ nipa awọn obinrin Jẹkri nikan, şugbọn ti oju irin (*Railway Stations*) ko nşe Jẹkri nikan, mo si ro pe bẹ na ni l' Eko pẹlu.

ỌLỌFADE.

---

## *Open Letters No. 14.*

---

To F. W. GARVEY, Esq.,
Commissioner of Police,
Colony, Lagos.

Dear Commissioner,

A squad of police stationed at Iddo are really making themselves a great nuisance by their most reprehensible manner in which they indulge always, to be arresting law-abiding citizens who happen to be on bike, on their way to and from Ebute-Mẹta.

It is stated on good evidence that however a cyclist may pedal as reasonably and as *slowly* as possible, these veritable Jack-in-office will entertain no scruples, to arrest such a one—perhaps for the fun of it—on an alleged charge of "riding furiously to the danger of the public."

I need hardly say how these unscrupulous "Bobbies" by an action such as this, are bringing the fair name of your Force into disrepute, having regard to a number of complaints with which I have been deluged.

An early check, by you, of the senseless and stupid practice, which I am sure DOES NOT receive your sanction, will undoubtedly serve as a relief to those who are at present the victims of police pranks arising from indiscriminate arrest of any BLACK cyclists who chance to ride between Iddo and Ebute-Meta.

With the season's compliments.

EKO AKETE.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday January, 6, 1923.

### ỌDUN ỌDUN NI, ỌDUN' RE, GBAI, LA O MA LOWO, LỌMỌ.

Ni gasikiya, olukuluku enia lo nfẹ pe ki ọdun ni ma ṣai "ṣe gbẹdẹ" fun on: eyi ko lẹ ṣe ko ma ri bẹ, nitoripe omi titun de, o si yẹ ki ẹja titun wọ inu rẹ. Niti wa, o to nkan bi meji tabi mẹta ti a nfẹ ko yọ'ri si rere lọdun ni.

Ekini—Pe ki gbogbo ayan ati ajo ti Ilu ti nṣe bọ lati ọdun keji wa, titi o fi di oni nipasẹ ti ọrọ Eleko Ọmọ-Alade lodọ Gomina Agba-Ọkunrin kọkọ-bọtọ maṣe jẹ asan, ati pe lai pẹ jọjọ ki Ijọba tun mu u bọ sipo rẹ.

Ekeji—Pe ki Igbimọ Ijọba ti Gomina agba npete ati fi ẹsẹ rẹ lelẹ ni iwọn oṣu diẹ ti mbọ, ma ṣai ṣe gbogbo ilu Nigeria yi ni rere, ati pe ki awọn ti a yọda fun ilu Eko lati yan sinu rẹ, ma ṣai jẹ ẹniti ifẹ ilu wọn yio gba ọkan wọn kan, ki o maṣe jẹ awọn amu'nu-ṣeka-m'odeṣotọ, tabi awọn aṣe-jẹjẹ-korodo ati bọ si ipo ọla.

Ẹkẹta—Pe ki airiṣẹṣe to kun ode isisiyi ma ṣai dinku, ati pe ki owo ati owo le tun sọji larin wa lẹkan si: a ko lẹ sọ iye ọgọrọ ọdọmọkunrin ti nwọn nwọ igboro kiri lakoko yi, lai ri kan-ṣekan bi obinrin ti o nji kawọbọ'tan.

Ẹkẹrin—Pe ki aisan "Ayọkẹlẹ" to nja wẹrẹwẹrẹ lode isisiyi ma ṣai buku, ati pe ki iku ojiji ti o ṣẹ dabi ẹnipe o nwọpọ ni Ilu wa yi ma ṣai re'lẹ.

Ninu Ipinu titun ti o jẹ aṣa awa oniṣokoto gbọrọ ati oni-yẹri, lati ma ṣe ni aṣẹṣẹ-bẹrẹ ọdun bayi, ẹjẹ ka ṣe olubori Ipinu, eyini ni pe ki Iṣọtẹ ati Tẹmbẹlẹkun si ara wa, irufẹ eyiti o ti sọ ọwọ ẹlomiran dilẹ nipa ṣiṣe sara ti ko ni gọm-bọ, fun didawo ọtẹ, eyiti o ti sọ ọmọ di ọta baba rẹ, ti o ti sọ aya di ọta ọkọ rẹ, ti o si ti sọ awọn ọrẹ meji di ọta ọrun ara wọn, ma ṣai jẹ ohun ti a o fẹku larin wa lọdun ni.

Ti a ba le ṣe eyi, dajudaju awọn enia ti nwọn njoye Agbọ-t'eku-wi-f'ẹiyẹ, ti nwọn ko ni iṣẹ meji ju pe ki nwọn ma fi ori alakeji wọn gba ara wọn yio "ko" gba iwa oraye wọn yi si 'le.

A si ntọrọ pe ki gbogbo Agan ma ṣai fi ọwọ wọn bọ osun lọdun ni: ki nwọn si ri ọmọ gbe' jo: ki alafia, ati Iwa-bi-Ọlọrun 'si ma bi si i larin wa, ati pe ki gbogbo awọn ologun-dudu-inu-ado ti nwọn ti jingiri si iwa ika le mọ pe "Aṣeni-nṣe'ra rẹ."

Lakotan, ara, Ẹku ewu ọdun titun yi, ki Baba ma ṣai fi ọpọlọpọ rẹ han ni, si atari ayọ ati alafia.

---

## Sir Donald Charles Cameron,

K.B.E., C.M.G.,

By the Editor.

*Reuter's Telegrams* of the 2nd instant announced the joyful news of another elevation of our energetic and popular Chief Secretary to the Government, The Hon. Donald Charles Cameron C.M.G., to the Knighthood of the Distinguished Order of the British Empire, by command of His Majesty the King. Our congratulations to the Honourable Gentleman on this well-deserved honour.

By the way, what of our local contemptibles who perhaps have been hoping against hope for an honour similar to this; when is their turn likely to come? any way, the community, we are of opinion, will not grudge their adding these dazzling and significant letters—K.B.—after their names, if gratuitously. The letters, for the benefit of our readers, mean no more than these—*Knight of the Order of the Boot i.e.* Kicking!!!. (*Verb Sap.*)

## ITAN AWỌN ỌBA EKO.

A o bẹrẹ itan yi lati sā Ijoba Ado, ẹniti o mọ Iga Idunganran. Ọmọ mẹrin ni Ọba Ado bi. Gabaro ni akọbi, Akiṣemọyin, Aṣipa kekere, ati Erelu ni awọn atẹle ọmọ rẹ. Gabaro ati Akiṣemoyin jasi ọmọ iya tanna. Li ọjọ kan bi awọn ọmọ iya meji yi ti nluwẹ ninu odo, ti nwọn si mu lọ si isalẹ omi gẹgẹ bi awọn omuwẹ ti ima mu lọ he okuta tabi apadi nisalẹ omi, nigbati nwon fo soke Akiṣemọyin eyi aburo he abẹrẹ ọba ninu omi. Lẹhin iku Ọba Ado Gabaro ọmọ rẹ agba gun ori itẹ. Li akoko yi Akiṣemọyin nṣe iranṣẹ fun awọn oyinbo ni ilu Egun, o si rọ ọ lọrun pupọ nitori anfan ti nrijẹ lara awọn oyinbo, ati pẹlupẹlu nitori ti oyinbo ko s li Eko nigbana. Ni ilu Egun si ni awọn ara Eko ima lọ ṣowo ẹru ; taba, ọti ati oniruru nkan oyinbo si nti ọna bẹ tẹ awọn Eko lọwọ. Arada ni orukọ ibiti nwọn npade na-ọja. Bi ọdun ba de, Akiṣemọyin a wa si Eko, a si ko ọti, taba, ati oniruru nkan daradara wa fun Ọba Gabaro ẹgbọn rẹ. Nigbati Ọba Gabaro ku, awọn Eko ranṣẹ si Akiṣemọyin lati wa ile. Soẹnu, Egbe ati Saṣi si ba wa ile lati ilu Egun. Nigbati o ti sinku ẹgbọn rẹ tan, awọn ara Eko fi jọba ni ipo ẹgbọn rẹ ologbe.

Nigbati Ọba Akiṣemọyin gun ori itẹ, o ran Ọṣọkeji ibatan rẹ ni idile iya lọ si ọdọ oyinbo ti o nṣiṣẹ fun ni ilu Egun pe, on jọba ni ilu baba on, on si nfẹ ki o ma wa ba on ṣowo pọ, ati pẹlu pe eti okun ni ilu on wa. Oyinbo na si mu ọkọ wa si okun Eko, ṣugbọn ko si awọn Aganyin ti yio tu ẹru wa ilẹ lati inu ọkọ oyinbo. Ọba Akiṣemọyin si tun ran Onisẹmọ Ọṣọkeji lọ si ilu Egun lati lọ mu awọn atukọ ati ọkọ Aganyin wa. Awọn Aganyin si mu ọkọ won meji wa. Lati igbana li Eko ti bẹrẹ si di ilu olokiki. Akiṣemọyin si ni Ọba to kọ fi awo kọ iga Idunganran. O ni owo pupọ, ati ẹru pupọ ; enia si pọ fun u li ọna gbogbo. Owo ẹru si jẹ pataki owo ilẹ yi nigbana. Diẹ ninu awọn Ojoye rẹ ni Soẹnu, Egbe, Saṣi ati Ọbaṣua.

Lẹhin iku Ọba Akiṣemọyin, Aṣipa Kekere aburo rẹ jọba ni ipo rẹ : ko si jọba ju oṣu meje lọ ki o to ṣe alaisi.

Lẹhin iku Aṣipa kekere, ijọba kan Erelu ṣugbọn nitori ti o jasi obirin, o fi ọmọ rẹ ti njẹ Ologun Kutere si ori itẹ dipo ara rẹ. Ọmọ mẹta ni Erelu bi, orukọ meji a ma jẹ Kutere ati Ṣokun ẹriki ẹkẹta ti o jasi obirin a ma jẹ Odu Asun-ba-oye-de. Olugbani ni orukọ iya Erelu. Ọkọ rẹ ti o bi awọn ọmọ rẹ mẹta fun a ma jẹ Ọlasọgba, baba to si bi Ọlasọgba jasi Ijẹṣa : awo Ifa lo ṣe wa si Eko, Ọlatunyin ni orukọ rẹ. On lo si fẹ ọmọ Ojoye kan ti Eko npe ni Aromirẹ.

Ọba Ologun Kutere lo si jọba tẹle Ọba Aṣipa kekere, ologbe ẹgbọn iya rẹ. O si jasi olokiki ọba o si ni owo ati ẹru pupọ. Awọn ọmọ Ọba Ologun Kutere to ogoji, ọkunrin ati obirin. Mẹta pere la si gbọ pe o jọba ninu won. Oruko awọn mẹta na ni wọnyi :—Ẹjibosu ti ujẹ Adele, Ẹṣilokun, ati Akitoye.

Ṣokun aburo Ọba Ologun Kutere joye kan ni Iga Idunmitafa ti o jẹ oye idile Erelu iya wọn.

Ẹṣilokun to jẹ akọbi Ọba Ologun Kutere Olọja Ereko ni idile iya rẹ ni igba aiye ọba baba wọn. Nigbati ọba baba rẹ gbọ, o sọ asọtẹlẹ ọrọ kan pe ẹniti o ba jọba lẹhin iku on yio ku nigbati o ba ti jọba li oṣu mẹta.

Lẹhin iku Ọba Ologun Kutere, awọn ara Eko mura, nwọn si nfẹ fi Ẹṣilokun jọba, ṣugbọn o kọ ; o si fa Adele aburo rẹ le wọn lọwọ lati fi jọba ni ipo baba wọn. Nwọn si fi Adele jọba. Ọba Adele a si ma lọ ki Ẹṣilokun ni alalẹ ni Ereko nibiti o gbe joye si.

Ẹṣilokun ni ẹgbọn obirin meji, ekini a ma jẹ Lanṣẹran, ekeji a ma jẹ Ọpọlu. Lanṣẹran fẹran Ọba Adele pupọ, ṣugbọn Ọpọlu ko fẹran rẹ.—*Iwe irohin Eko—1889.*

---


## MERCHANTS AND TRADERS

*PLEASE READ AND ACT.*

Four Reasons why you should advertise in "Eko Akete" a popular Yoruba Weekly.

**(Published every Saturday.)**

1. Because it is the only Vernacular weekly newspaper published in Lagos for the benefit of all Yoruba reading public in British West Africa of which Nigeria forms no inconsiderable part.

2. Because any advertisements submitted are generally translated into Yoruba in a particularly fascinating style which cannot but attract many customers to your Establishment.

3. Because Yoruba language, being spoken and read by a greater number of the people both here and abroad, stands the chance of making your advertisements in Eko Akete welcomed and appreciated by the masses.

4. Because any advertisements in the language of the people of the country are the best medium for profitable results at all times

For Rates, etc.,
Apply at P.O. Box, 286.
or at EKO AKETE Office,
24, Williams Street, Lagos.

## Correspondence

To the Editor of "Eko Akete"

Sir,

Please permit me to put before you the uncivilised conduct played by those who called themselves Christians at Ikorodu.

Two months ago a man by name Mr. D. O. Legunsen was written to by the Ikorodu Unity Club eastablished in Lagos to preside on Xmas day over their "Sport." This gentleman replied the Club in a letter dated 5/11/22 at Ikorodu giving his consent and his members to attend the play, and the members of the said Club paid him a visit on 3/12/22 and separated with good spirit after the notices were printed and placarded right round the Town of Ikorodu rumours came out that this Club was composed of nothing but members Brotherhood Christian Church then the people of the Town were prevailed upon not to attend; also letters were written round the Churches of C.M.S., Wesleyan, and Bethel that this people who are coming will bias their members and induce them to join their own Church. (Brotherhood.)

The announcement was made in the Ikorodu Churches on Sunday the 17th Dec. 1922 (a week's time pre the sport.) On the Sport Day being Christmas Day the Christians were all at home but none of them (C.M.S. Wesleyan and Bethel) ventured to attend the Sport, if memory serves me well you could only see one Bethelite on the stage.

But God will not leave His people for the play was a splendid one ever performed even more than what members expected though the attendance are Mohammedans and Pagans and the addresses were delivered by Messrs Ladega, Akidebin Johnson and one Mohammedan whose name escaped me, spoke on the words of encouragement and unity etc., etc.

The play was closed with a song by the members thus :—

God bless the Boys 'Krodu, Our future hope and joy
Grant all that may be needful,
For life and godliness ;
The Boys of happy 'Krodu,
Bless them at home, abroad
God bless the Boys and maidens
O God, Our fathers' God !

The play came to an end at 7 p.m.

AKIN: ONI-ORISAN
*Secretary.*

[If this so, then our Christian friends in this place are no better than those Pharisees who were denounced by CHRIST as Whited sepulchres.
ED. E.A.]

---

## Ẹ ṢU RIGIDI BO MI O!

OWO IRANLOWO TI A ṢI RI GBA NI WONYI.

| | | £ | s | d. |
|---|---|---|---|---|
| Owo ti a ti ri gba | | 11 | 16 | 9 |
| Ọgbẹni J. Oṣodi | ... | 0 | 5 | 0 |
| „ J. Ọkọosi | ... | 0 | 5 | 0 |
| Aropọ | | £11 | 6 | 9 |

Ara ilu, Ẹ jare Ẹ ma jẹ ko rẹ nyin,
A o ma jihin yi lọsọsẹ.—[ED.—E. A.]

---

## IWE IKEDE TI ILU, IGBIMỌ TI EKO.

Iwe Orukọ awọn to nvan Enia sinu Igbimọ yi.

A kede pe gẹgẹbi Ẹsẹ Kẹfa ti Ofin Igbimọ Eko ti a mọ bi "Munisipa" ti ọdun 1919, ti wi, ẹnikẹni le lọ yẹ Iwe-orukọ awọn ti nyan enia si Igbimọ yi wo ni Ile-iṣẹ Sẹkitẹri Igbimọ na fun ijọ mẹrinla lẹhin Akiyesi yi.

Ni Akoko yi, Ẹnikẹni le kọwe si Sẹkitẹri na pe ka fi orukọ on kun, tabi ka yọ kuro lọhin ti oluwa rẹ ba ti kowe fi fi eredi nkan bẹ hani si Sẹkitẹri.

A. W. S. RUMENS
Sẹkitẹri, Igbimọ Ilu.

Ọjọ karun oṣu January, 1923.

22, Apatira Street, and
34, Palm Church Street,
Lagos, 6th January. 1923.

I beg to inform the public in general that I am now a Headman of "Esu" in Lagos, for everybody who wishes to join same; it commences from 10/- to £5 every Calendar month from any one who wishes to join same; as long as you can subscribe it is only for six months, before you can receive your share and six pence will be my commission on £1. 0 0.

2. And another commences from 1/- to 10/- every week for any one who wishes to join the "Esu" for three months before you can receive your share and my commission will be six pence on £1 0 0.

3 I may bring to your knowledge again that if you keep long in "Esu" and you want some amount to use, I will help you before you finish your share.

4. I get a certain amount for it to start same, if anybody wishes to join this "Esu" he or she should see me at 22, Apatira. Street, or 34, Palm Church Street, Lagos.

*Another due date for the above is 31st January 1923.*

ABUDU WABI BAJELA.

---

"VESTA".

Treadle Sewing Machines for sale at same address. Prices moderate.

---

ỌMỌ YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"
Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,
Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,
Ihin ko to afojuba
A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ko.

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onișowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

ni wal·iwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ñi lọ.

---

"EKO AKETE"

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ awọn Aṣoju wa wọnyi.

LAGOS.

1. Ajenifuja Stores, 109 Broad Street.
VIDAL R. COLE.

IBADAN.

Ọgbẹni A. M. Suberu Santo's House. Gbagi Street.

ZARIA.

Ọgbẹni A. Ẹkundayọ Cole, Accounts Office.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Moiracithin pill sand get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neurasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/-. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store P. O. Box 201 ;109 — VIDAL. R. COLE Broad Street Lagos

# Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)
Masses Isin Arọ,
6.30—7.30 8.30—0.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m.—Christ Church The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit)
Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
6.30 p.m. do do
9 a.m.—St. John's (Arọlọya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do do
9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) Rev. J. A. Cole
9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero)
Rev. S. J. Gansallo.
9 a.m....St. David's (Jordan) Rev. J. A. Leigh

**WESLEYAN**

10.30 a.m.—Tinubu Rev. A. N. Cole
7 p.m. Rev. J. C. Cole
10.30 a.m.—Ereko Rev. E. K. Ajai-Ajagbe
7 p.m. " "
10.30 a.m.—Olowogbowo Rev. E. E. Williams
7 p.m. do. do.
10.30 a.m.—Ọbun Eko Rev. D. A. Beckley
7 p.m. do. do

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m.—Jehovah Shalom Rev. Supt. G. A. Oke
7 p.m " " "
9 a.m.—Erelu Bro. J. H. Lawson
4 p.m. do do
9 a.m.—Bethel Suptd. J. S. Williams
6.30 p.m. Rev. J. Ṣotayọ Williams
10.30 a.m.—African Methodist Rev. I. O. Oyekunle
4.30 p.m. Bro. E. A. Williams
9 a.m.—Ararọmi Church Rev. E. C. Alabi
4 p.m. Rev. A. A. Puddicombe

**EBENEZER**

9 a.m. Bro. E. A. Ojo
6.30 p.m. Rev. E. C. Alabi

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m.—Ilupesi Pastor A. Adedeji Iṣọla
9.30 p.m. do. do.

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA**

6 a.m.—Faji Service Bro. Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajoṣẹ
(Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

**Sunday, January 7th, 1st Sunday after Epiphany**

8 a.m.—Holy Communion Rev. H. A. Lewis
6.45 p.m.—Evensong and Sermon do


## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni

"MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan ; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Ivẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

## EMANUEL J. ADE DAWODU

Tailor and Draper

27, Daddy Alaja Street,

Perfect Fittings Guaranteed.

---

## Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o ṣi "Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,

Ogun rẹ jire.

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia, Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAṢINI-ARANṢỌ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAṢINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara' Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipon ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AṢIRI nipa Owo. IROHIN KO TO A ỌIUBA.

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary*.)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa n; Popo-nla (*Broad Street*,) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser*.) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kôtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita; awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromire. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan.

Ibaşe fun Orififọ. Inurirun, Ẹda, Inarun, Arun Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sibin tan.

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba. Iwọ ko tilẹ gbọ orukọ rẹ adan?

Işẹ Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG, *Alabojuto*.

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kowe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo onişowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorişirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'. ko.

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

AWON ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18, GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranşẹ ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ' ibaşe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jo enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi şowọ lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Forlo-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa şa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.